Bibeli fun awon omode

# Jesu yan Oluranlowo mejila



Akosile lati owo: Edward Hughes

Ayaworan: Byron Unger; Lazarus
Alastair Paterson

Olu'lo: E. Frischbutter; Sarah S.

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2023 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi,
niwon igba ti o ko so di owo.

Jesu se awon nnkan iyanu. O wo oniruuru arun san, O fi alaafia fun awon ti okan won ndaamu, O si n koni ni oro Olorun.




Ijo eniyan wa si odo Jesu fun iranlowo ati iwosan.
O pinnu lati yan okunrin mejila laarin opolopo awon
omoleyin re, lati ma a ran lowo ninu
ise re si Olorun.



Bi o ba ni awon ipinnu pataki lati se, nje o ma n gbadura si Olorun? Jesu se bee! Ni ori oke didake kan, O ba baba re ti n be lorun soro. Jesu gbadura titi oorun fi wo.


Jesu fi gbogbo oru naa gbadura.

Ni owuro, Jesu pe awon omoleyin re, gbogbo awon ti won ntele E, ti won si gboran si lenu. Laarin won O yan mejila ti yoo je Oluranlowo pataki tabi apositeli.



Awon meji ti Jesu koko yan je arakunrin ara won, Simoni Peteru ati Anderu.  Won ti fi ise apeja won sile nigba ti Jesu koko pe won lati tele oun.



Jakobu ati Johanu, awon omo Sebede, tun ti fi awon ipeja won sile.



Jesu tun yan Filipi, Batolomiu, Matiu, Tomasi, Simoni ti se ajijangbara, Jakobu omo Alfeu, Judasi arakunrin Jakobu ati Judasi Isariotu eni ti o pada diota Jesu.





Jesu ko won pe sise ohun ti Oun nko won dabii ki eniyan ko ile si ori ipile ti o duro daadaa. Afefe iji lile ki yoo le ba ile naa je.

Sugbon aigboran si oro Jesu dabii ki eniyan ko ile si ori ipile oniyanrin. Nigba ti iji ba de, ile naa yoo wo lule.



Awon ase Jesu kan wa ti  ko rorun lati pamo.  Jesu ko won wipe “Bi eni kan ba gba ereke otun re tun ko ti osi si.  Feran awon ota re.”

Awon eniyan nilo iranlowo Olorun lati gbe igbeaye won bii Jesu.



Jesu tun so fun awon eniyan lati maa gbadura ni ikoko - ki won mase afihan adura niwaju opo eniyan bi awon adari esin kan se n se.



Jesu so wi pe Olorun yio bo awon eniyan ti o fi igbekele won sinu re, yio si daso bo ihoho won. Niwon bi Olorun ti n fun eye ni ounje ti o si fi awo daradara fun ododo ati itana, awon eniyan re le fi igbekele won sinu re fun gbogbo aini won.



Jesu ko awon oluranlowo re titun ni opolopo nnkan lojo naa. Nigba ti o pari, adete kan wa, o n be Jesu pe ki o wo ohun san.





Jesu da adete naa lohun “Mo fe. Di mimo.” Bi awon omo-eyin tin wo o, adete naa di mimo. O ti gbaiwosan! Omo Olorun nikan ni o le se eyi. Awon omo-eyin mo pe won ni agbayanu aladari.

Jesu yan Oluranlowo mejila

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Matiu ori kerin titi de ori keje,
Marku ori kin-in-ni, Luku ori kefa

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi Ori kokandinlogofa ese adoje

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun
iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe: Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo!
Johannu ori keta ese kerindinlogun.